***Kín ni àkóbá tí ìyípadà ojú ọjọ́ lè ṣe fún oko adìyẹ rẹ?***

Ìyípadà ojú ọjọ́ máa ńfa wàhálà ooru àti àìbalẹ̀ ara púpọ̀ fún àwọn adìyẹ. Wàhálà ooru àti àìbalẹ̀ ara yìí ń ṣẹlẹ̀ látàrí àsìkò ooru t'ó gbóná ju bí ó ti yẹ lọ tàbí nígbà tí àwọn adìyẹ bá kojú ọjọ́ bíi mélo kan tí ó gbóná jọjọ. Níwọ̀ngbà t'ó jẹ́ wípé oúnjẹ jíjẹ adìyẹ máa ń dínkù pẹ̀lú bí ooru bá ṣe pọ̀ sí, wàhálà ooru ní ipa lórí gbogbo ipele ọ̀sìn adìyẹ: lòrí dìdàgbà, lòrí iwọn àti dídára ẹran àti ẹyin adìyẹ àti pàápàá lòrí adánidá adìyẹ láti dènà àìsàn. Ooru àyíká t'ó bá ti kọjá ìdiwọ̀n ọgbọ̀n (30-degrees Celcius), èyí tí ó wọ́pọ̀ lásìkò yí, máa ń dín títẹ̀wọ̀n àwọn adìyẹ kù, á sì máa ṣokùnfa ikú ọ̀wọ̀ọ̀wọ̀. Ó ṣeéṣe kí o ti ṣe àkíyèsí wípé tí omi mímu bá gbóná, adìyẹ kò níí mu omi, wọn kò sì níí jeun dáradára. Èyí já sí ẹ̀dínkù iye ẹyin adìyẹ àbọ̀yé àti títóbi adìyẹ àbọ̀pa. Ní àfikùn, ìwọ̀n ooru tó ga ju máa ńṣe okùnfa pípọ̀si àjàkalẹ̀ àrùn. Lápapọ̀, ìyípadà ojú ọjọ́ léwu fún yíyé, pípamọ́ àti dídàgbà adìyẹ. Bí ìdàgbàsókè iṣẹ́ ọ̀sìn adìyẹ nípa yíyé, pípamọ́ àti dídàgbà bá wá relẹ̀, èrè lórí ọ̀sìn adìyẹ yíò dínkù, àgbẹ̀ yóò sì mọ̀ọ́ lára.

***Kíwá ni o leè ṣe báyìí?***

Ìròyìn ayọ̀! Àwọn ọ̀nà àbùdá wà tí àgbẹ̀ lè gbée gbà ní kíákíá láti dín ipa wàhálà ooru kù. A ti bá àwọn àgbẹ̀ bíi tìrẹ sọ̀rọ̀ ní àsìkò ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àti àbẹ̀wò sí oko wọn.

Àwọn àgbẹ̀ wọ̀nyí jẹ́ kí á mọ àwọn ọgbọ́n tí wọ́n ńta láti dín ipa tí ìṣòro ìyípadà ojú ọjọ́ ní lórí ìdàgbàsókè ọ̀sin adìyẹ wọn kù jọjọ. Ìwọ náà lè mú àwọn ọgbọ́n yìí lò.





*Orísun: Àwọn Olùkọ́wé*

***Báwo ni o ṣe lè dín ipa ìṣòro ooru àti àìbalẹ̀ ara kù lórí oko ọ̀sin adìyẹ rẹ?***

- Yẹra fún sínsin adìyẹ aláwọ̀ dúdú nítorí wọ́n máa ń gba ooru sára púpọ̀
- Pèsè àyè fún atẹ́gùn láti máa fẹ́ẹ́ dáradára nínú ilé adìyẹ rẹ
- Fún àwọn adìyẹ rẹ ní èròjà aṣara l'óore "Vitamin C" àti tọ́níìkì nínú omi wọn



*Orísun: Àwọn Olùkọ́wé*

- Tí ó báá ṣeéṣe o lè wá ẹ̀yà adìyẹ "Shika Brown" tàbí "FUNAAB Alpha" fún sínsin nínú oko rẹ. O lè tún máa sin àwọn ẹ̀yà adìyẹ aláwọ̀ funfun tàbí aláwọ̀ míràn tí ó lè fi ara da ooru



- Àwọn ìgbésẹ̀ láti d'ènà àìsàn ṣe pàtàkì púpọ̀. Tẹ̀lé àwọn ìlànà fún abẹ́rẹ́ àjẹsára àti òògùn lílò fún àwọn adìyẹ rẹ
- Ó dára kí á fún adìyẹ ní oúnjẹ ní bíi wákàtí mẹ́rin sí márùń kí ooru tó mú dé góńgó fún oúnjẹ láti dà tán n'íkùn kí ooru tó dé rárá. Èyí á jẹ́ kí púpọ̀ nínúu oúnjẹ tí àwon adìyẹ náa jẹ di èròjà ara
- Fún àwọn adìyẹ rẹ ní àwọn òògùn tí yíò dá ààbò bò wọ́n l'ọ́wọ́ọ wàhálà ooru kí ara wọn lè mókun l'ákokò ooru

***Báwo ni o se lè pèsè àyiíká tí ó silé àti omi tí ó tutù fún adìyẹ rẹ nígbà tií ooru bá ń mú?***

- Gbin àwọn igi tàbí irè bíi ọgẹdẹ láti pèsè ibòji fún àwọn adìyẹ rẹ
- Máa pàrọ̀ "litter" déédé láti d'ènà àkójọpọ̀ àwọn afẹ́fẹ́ẹ́ gáàsì tí kò dára nínú ilé adìyẹ
- Máa ṣe àkíyèsì àwọn adìyẹ rẹ láti lè mọ iye tí o lè kó sínú ilé kan lâì ṣe ìdíwọ́ fún lílọ bíbọ̀ wọn àti jíjágeere atẹ́gùn. Èyí jásí wípé o lè nílò láti dín iye adìyẹ tí ó yẹ kí ó wà nínú ìdiwọ̀n àyè ilé kan tàbí nínú àgò kan kù
- Lo àwọn iná ìgbàlódé tí kìí gbagbára púpọ̀ tí kìí sì móoru jù
- Ri àwọn ọ̀pá tí ó gbé omi wọlé adìyẹ mọ́lẹ̀ kí omi lè máa tutù
- Ń'jẹ́ ìwọ ń gb'èrò láti ní odò ẹja? Ó dára, nítorí ó lè ràn ọ́ lọ́wọ́ láti lè máa rí omi tútù tí o bá dá odò ẹja sóríí ilẹ̀ kan nàá pẹ̀lú oko adìyẹ
- Wọ́n ìrì omi fẹ́ẹ́rẹ́fẹ́ sí àwọn adìyẹ rẹ lára láti jẹ́ kí ará tù wọ́n nígbà tí ooru bá pọ̀ lápọ̀jù
- Tí o bá ń lo àgbá omi ìgbàlódé láti tọ́júu omi, o lè máa da omi tí ó bá ti gbóná nù kí o sì fa omi tuntun tí ó tutù sínúu rẹ̀ láti inúu kànga d'ẹ̀rọ ní gẹ́lẹ́ tí o bá fẹ́ fún àwọn adìyẹ rẹ ní omi. Tí ó bá sì jẹ́ kànga ni ò ńlò láìsí àgbá omi, o lè máa faa omi t'ó tutù t'ó sì tòrò ní gbogbo ìgbà tí o bá fẹ́ fún àwọn adìyẹ rẹ ní omi. Èyí yíò jẹ́ kí

àwọn adìyẹ wọnyí máa gbádùn omi tútù tí ó dara, wọn yíò sì jẹun dáradára

- O lè gbé àwọn àgbá omi sínú ilé adìyẹ láti d'ènà ìtànsán òòrùn tí ó lè mú kí omi gbóná lójú ọsán
- Bí omi bá wá gbóná síbẹ síbẹ, ju yìnyín sínúu rẹ kí ó lè silé

### *Àwọn ńkan míràn wo ni o ní láti fi s'ọkàn fún ojọ iwájú?*

- Ní àfikún sí gbogbo àwọn ìlànà ìṣàkóso olówó táṣẹrẹ tí ó rọrùn tí a tí la sílẹ, ìwọ pàápàá lè bẹrẹ síí ṣe ètò sílẹ fún ọjọ iwájú. Àwọn onímọ ìjìnlẹ "science" ti sọ àsọtẹlẹ pé ó ṣeé ṣe kí ipa ìyípadà ojú ọjọ yí ó le síi ní agbègbe waa bí àwọn olùdarí l'ágbàáyé kò bá f'ẹnu kò l'órí ọnà àbáyọ làti d'ènà àwọn ńkan wọnyí
- Bí o bá ń gb'èrò láti kọ ilé adìyẹ titun, o nílò láti fi àwọn kókó kan sọkàn nípa bí ilé náà yíò ṣe dúró. Oòrùn ńyọ láti ìlà-oòrùn ó sì ńwọ sí ìwọ oòrùn. Látàri bẹẹ, ẹgbẹ ibi tí ó gùn jù nínú ilé adìyẹ gbọdọ d'ojú kọ àríwá àti gúsù. Nípa bẹẹ ìtànsán oòrùn tíí yíò wo inú ilé adìye náà yíò dínkù, ilé adìyẹ bẹẹ yíò sì máa silé
- Ríi dájú pé àjà ilé adìyẹ náà ga dáradára, kí ògiri tí o mọ sí ìsàlẹẹ rẹ má sì ga rárá fún atẹgùn láti lè fẹ yíká dáradára nínú ilé adìyẹ
- Máa lo ìgbà àti bí ooru ṣe mú sí láti díwọn iye adìyẹ tí oóò kó s'ínú ilé kan

Bí ó bá ṣe ìgbèríko ni oko rẹ wa, kàkà kí o fi símẹntì mọ odi yíi ká, o lè fi wáyà onírin ṣe ọgbà. Èyí yíò dáàbò bo oko rẹ, yíò sì tún jẹ kí atẹgùn fẹ dáradára ju ti odi oní símẹntì tàbí búlọọkù.



Ó dára láti lo abala "aluminium" tàbi "asbestos" láti ṣe òrùlé ilé adìye ju ti "Zinc" lọ, nítorípé "Zinc" máa ń fa ooru sínú ilé adìyẹ. Fún àwọn ilé adìyẹ tí o ti kọ tẹlẹ, o lè fi ẹrọ af'átẹgùn s'ínúu wọn kí atẹgùn lé fẹ dáradára fún àwọn adìyẹ.



*Orísun: Àwọn Olùkọwé*

Fún àmọràn síwájú síi tàbí ẹkúnrẹrẹ àlàyé l'órí ìwé ìlẹ́wọ yìí, kàn sí: Dr. Kazeem Bello (Federal University of Agriculture Abeokuta) kazeembello19@gmail.com +2348032204658; Dr. Buba Wahe (NAERLS, Ahmadu Bello University, Zaria, bubawahe@gmail.com +234806539885), Dr. Toba Adeyeye (+2348083058853) tàbi Dr. Saweda Onipede Liverpool-Tasie (Michigan State University, lliverp@msu.edu). Ttranslated by Dr. Olalekan Oyekunle, Media and Farm Broadcast (MFB), AMREC, Federal University of Agriculture, Abeokuta (FUNAAB) and Mr. Idris Taiwo Olabode - MFB, AMREC, FUNNAB,

Ìwé ìléwọ yìí ni a tẹ jàde làti ọwọọ àkójọpọ àwọn ènìyàn àgbáyé kan tí wọn ní ìtara nípa ọrọ ìyípadà ojú ọjọ àti bí oúnjẹ tí ó péye yíò ṣe pọ yanturu l'órílẹ ède Nàìjíríà (Nigeria) pẹlú ìrànlọwọ láti ọwọ àjọ *Feed the Future Nigeria Agricultural Policy Project* àti *Michigan State University's Alliance for African Partnership*

Feed the Future Innovation Lab for Food Security Policy

Nigeria Agricultural Policy Project

&

Alliance for African Partnership

November 2018

## Ìwé Ìléwọ Atọnisọnà fún Ọsìn Adìyẹ tí ó Péye lábẹ Ìyípadà Ojú Ọjọ

## (Manual for Better Poultry Management Practices with Changes in Climate)



*Orísun: Àwọn Olùkọwé*

### *Kín ni ìyípadà ojú ọjọ?*

Ìyípadà ojú ọjọ jẹ àwọn ìyípadà ọlọjọ-pípẹ tí ó jẹyọ nínúu ètò bí ojú ọjọ ṣe máa ńrí láti ìgbà dé ìgbà. Èyí ni ó ń farahàn látàri ìwọn ooru àyíká t'ó ga, àrọọrọdá, àìṣedéédé, àti ségesège òjò, àìlèsọ bí ojú ọjọ yóò ṣe rí, àti àwọn ìṣẹlẹ t'ó ń jẹ yọ lemọlemọ.

Kìí síí ṣe gbogbo àwọn ìyípadà náà ni a kò lè ṣe àkíyèsí wọn láti ọjọ de ọjọ àti ìgbà dé ìgbà. Ṣùgbọn lẹhìn ìgbà pípẹ, àwọn ìyípadà wọnyí lè ṣe àkóbá fún oko àti akitiyan rẹẹ lórí iṣẹ ọsìn.